# ELETI ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ...

VOL XIV NO 847 LAGOS SATURDAY DECEMBER 1st — DECEMBER 7 1962 KOBO MEJI (2D)


Ejo Awon Olote:

# Sumbo Jibowu Tu Asiri Sita; O Ni Ile Akintola Ni Nwon Ni Ki On Fagba Fo

EKO—Adajọ-agba Ọgbẹni G. Ṣowẹmimọ fi okele lẹ ọrọ atako ti awọn agbẹjọro lọya tako ọrọ iwe akọsilẹ ti Sumbọ Jibowu, ọkan ninu awọn enia merinlelogun ti awọn ọlọpa nnu ro ẹjọ wipe nwọn ditẹ si Ijọba, kọ, wipe ko nṣe ifẹ inu rẹ ni o fi kọ ọ; awọn Ọlọpa ni nwọn nnu lagbara kọ ati wipe nwọn ṣe ileri fun un. Adajọ na ni on gba wipe ifẹ inu Sumbọ ni o fi kọ iwe akọsilẹ na.

Iwe akọsilẹ meji ni awọn Ọlọpa mu wa siwaju adajọ wipe Sumbọ Jibowu kọ fun awọn, ninu ọkan o sọ bi on tiṣe pade Aluko kan ti o ni ki on ba on ko ẹtu ifọkuta pamọ fun on ni oko ẹgbọn on ni abule kan leti Agege.

Lẹhin eyi awọn tun sọrọ lori rogbodiyan ti o ṣẹlẹ nigbana ni ilu Ibadan larin awọn oṣelu. O ni ninu iforọ iwe ọrọ yi ni awọn ti ro iṣẹ jamba ti awọn fẹ fi ẹtu ifọkuta na ṣe. O ni awọn kọkọ ro wipe petesi gogoro ti Oloye Akintọla kọ si Onikan l'Eko ni ki awọn kọ fọ bamu bamu, ki Akintọla na le mọ wipe on ko to lẹnu ọrọ na rara lati ba Awolọwọ, olori ẹgbẹ awọn ja.

Sumbọ ni nigbati awọn gun mọto de idi ile na, on ri wipe a ṣe ọpọlọpọ awọn alaisan ti o wa ninu ile alaisan leti ile na leṣe ti awọn ba ni ki awọn lọ ile na. O ni eleyi wa jẹ ki awọn pinnu lati wipe ki awọn kuku lọ fọ ile ti Akintọla kọ si Oke Ado ni Ibadan.

Iwe-akọsilẹ ti ẹlomiran ninu awọn arufin na ti nwọn tun ka si etigbọ awọn ero iworan ni Kotu ẹri ti M. A. Omishade tiṣe lọya. Ọga ọlọpa na ni ọdọ Dokita M. A. Majekodunmi adele alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Oorun ni on ti pade Omishade pẹlu Dokitu Shodipọ lojọ ti on nuu. Omishade paapa ni Dokita Majẹkodunmi ni ki awọn Ọlọpa yinọọn fun on ti on ko ba ran wọn lọwọ ọrọ onibọn ti nwọn nwa.



Majekodunmi

## AWOLOWO LA ALA EJO

Ṣaju eyi nwọn ti ka iwe kan ti nwọn ri ko ninu ile Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ninu eyiti o kọ ala kan ti on la lori ọjọ kan si wipe on ti ẹ̀jọ nla kan ti o di on lọna, on si mu ọpa ti o wa lọwọ on, on fi pa a. Ni aisẹ ani-aul on ri wipe on ti ṣẹgun awọn ọta on, awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu ti nwọn npe ni NPC ni Oke Ọya ni Ipinlẹ Ariwa niyẹn.

O ni ti Ọlọrun ba ṣe e ti on fi le gun ori aga Alakoso Ijọba Apapọ̀ṣe (Prime Minister) lẹhin idibo ọdun 1959, on yio fa agbara on lati ṣe rere fun gbogbo wọn ara ilu Nigeria nibikibi ti nwọn ba ti wa.

(Wo yoku loju iwe kẹjọ)


## LAGOS RACE CLUB

### CHRISTMAS MEETING 1962/63.

SATURDAY 22nd, WEDNESDAY 26th, SATURDAY 29th DECEMBER, 1962. TUESDAY 1st AND SATURDAY 5th JANUARY, 1963.

Provisional Programme and Entry Forms can be obtained on application to the Secretary, P.O. Box 51, Lagos or at the Race Course, Lagos.

Note — No Entry fees will be refunded after the draw has been made.

Entries close at noon on Monday 10th December, 1962.

No Cheque will be accepted.

C. H. E. MILLER
Hon. Secretary.

Ayiluka Ni:

# Oloye Ojikutu So Aiye Alapata Dero

Gegebi mo ti so fun enyin okawe mi ni ose ti o koja wipe ma tun soro lori oro awon omo egbe Alapata eran l'Eko ti nwon ni awon ti ro Baba egbe won, Oloye Abudu Yekini Ojikutu, Balogun awon ara Eko, loye ni o tun je ki nki Oloye na ni oriki bayi: Oloye Ojikut atose mase, ato se ka se suru. Mo ni Oloye Ojikutu se kisa ise fun awon alapata eran Eko sugbon aimore ni o fa oro ija won, awon na si hu'wa a fi ibi su olore.

Sugbon bi o ti wu ki awon paapa je amumi agbon to, ko ye ki nwon gbagbe odun 1957 ti ise won alapata wo lule bi igi. Osu merin gbako ni nwon fi yan elebe pataki lati lo ba olori won yi pe ki o ba awon tun ise na se. Oloye Ojikutu si dide o si sebe.

Gegebi ise apata ti je ise Ogun, olori won na si se ibere si oro na lodo awon agbalagba. Odu ifa ti o si jade si ibere na ni awon Egba fi te ilu Abeokuta do lojo kinni. Odu na si lo bayi: "Otoro aiye je, Ogbalaja aiye la kanle, agogo orun nro kango kango, gbedu orun nro kiriji-kiriji, agba nla ma ro kiriji-kiriji, lo da fun Orunmila lojo kinni nigbati o mbo wa saiye ti aiye Onife baje.

"O ranse si Olola lode Ado, o ranse si Erinmi lode Owo, nwon ranse si Pepe lode Asin, nwon ranse si Esegisa awo Egba. Gbogbo won se aiye Onife nwon se e ti, asehinwa asehinbo won wa ranse si omotuntun afatese tingindin, Omotuntun wa de ti on tewe Olusuwalu. Ewe Olusuwalu ni Omotuntun wa fi tun aiye Onife se."

Nje Oloye Ojikutu wa di ewe Olusuwalu, Olusuwalu Omotuntun afatese ringindin. Ki Olorun ko fori jin Alhaji Sule Layiwola ati Salami Egba, ko si lora emi Alhaji Salami Adelakun ati awon omo ehin won, Lawani Madoutola, ki o tete pada ninu isina re. Awon mereria nwonyi ni nwon se okunfa bi Oloye Ojikutu tise dide lati tun ise apate eran se lehinti nwon ti bebe titi bi osu mefa gbako. Nitori iwa aimore alehinwa, Oloye Ojikutu fi nake kori wipe ayafi ti awon alapata ba fi owo si iwe adehun.

Nitoto gbogbo awon ti o je alapata lojo na lohun ni nwon lo si Kotu gan-ran lati lobura (affidavit) niwaju akowe kotu-agba ni ikokan. Oloye Ojikutu si dide o ba awon alapata pin eran pipa larin gbogbo awon alapata ti nwon ni iso eran l'Eko ati ni Ebute-Metta.

Enikeni ko si gbodo pa ju iye eran ti nwon bu fun un lo nipa agbara iwe adehun ti nwon fun Olori won na ni Kotu-ganran. Nipa bayi ise apata wa do-tun. Opolopo awon omo Ibadan ti nwon nse ise alapata, ti nwon ti je gbese ile, ni nwon di eniti nwon wa nzin ti nwon nyan falala, ti nwon nra ile, ti nwon nko ile nigbati ere ise na de. A ko si sai ni ti to larin ogun tabi ogbon larin won ti o je wipe nigbati nwon ko ile won na pari tan, Oloye Ojikutu ni nwon ni ki o ba won si i.

Oloye Ojikutu so aiye awon alapata d'ero, kinni e wipe Alabi tun se? Bi awon alapata ko ba je afibisu-olore ko lo si nwon rara ki nwon doju ota ko baba-egbe won yi nitori oro kekere ti o sele larin awon alapata ati dokita Minisita pelu Oyinbo Ika si Eranko ko Dara.

Bi gbogbo alaye mi yi ba dabi iro, ki e da mi lohun ninu iwe irohin Eleti-Ofe ni ose ti mbo.

# Iya Eto Alaso



Aworan ti e nwo yi ni ti Oyinbo obinrin kan ti o nse eto aso ti awon egbe elere kan ti nwon fe wa si Ipinle Iwo Orun Afirika lati wa se ere fun wa yio wo. Ibiti nwon yio ko gbe se ere won na ti nwon bade ninu odun ti mbo ni ilu Ibadan. Orisirisi aso-wiwo ni nwon yio si mu lowo fun ere alarinrin na. Lehin eyi nwon a lo si Ghana ati Saro (Sierra Leone).

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

LATI ỌWỌ AYILUKA
"Ori-Ade"

Iku doro, iku pa "Ori-ade Jenkins". Anu ṣe mi pu o lati tu ọfọ ọrẹ mi kan ti o r u k ọ rẹ njẹ James A. Akande ẹniti awọn ọtunlogo enia ni ilu E k o mọ adape orukọ rẹ ni "ORI-ADE JENKIS" ti o jalaisi ninu ọsẹ ti o kọja ni 40, Kọsọkọ Streeet, Alakoro l'Eko. Awọn atata enia lọ'unrin ati lobinrin si sin oku rẹ.

Ẹni ọdun mẹtalegọta ni ologbe na, ọmọ Ijaiye ni agbo ile kan ti nwọn npe ni Ile Amọọ ni Abẹokuta ni i ṣe ṣugbọn ni ati kekere ni o ti de Eko. O jẹ ẹnikan ti o ni ọyaya pupọ, o si le ki ni tẹrin tẹrin. Emi ko ri lọjọ kan ki o binu ri. O si gbajumọ ni i w ọ n b a ti ọmọluwabi.

Mo ki ẹnyin ọrẹ ati ẹbi "Ori-Ade," ẹ ku asẹhinde, ẹ ku inawo, Ọlọrun jẹ ki ọjọ ko jina si ara wọn.

"Ori-Ade Jenkins," ọrẹ mi re ! Ki o mọ jẹ ọkun ki o si m[illegible] lọhun ni ki o ma jẹ.

# Ayun A di mowo



**Ayun elero a-di-mowo tuntun ti enia le lo nibikibi ti awon Oyinbo Gesi sese se fun awon onise gedu niyi. Epo petiro ni o nlo, o si wulo fun awon agbe ati awon asogbo pupo.**

## Kereni Tuntun

Emi Ayiluka ti gbọ ọrọ kan finrin nipa kereni tuntun ti awọn alakoso Ijọba Apapọṣe wa fẹ kọ si ilu Eko wipe awọn Oyinbo ajoji kan ti fọwọ sọ aya fun wa nipa owo ti a o fi kọ ọ.

Olofofo ti o ṣe ofofo fun mi ni orukọ awọn Oyinbo na ni a npe ni West Germany; ọrẹ wa ni nwọn nṣe. Nwọn ni awọn yio ba wa w[illegible] owo gọbọyi bi 21 million pound lati fi ṣe kereni na.

## Owo Tuntun

Bi nwọn fẹ fi owo na fun wa di ọjọ kojọ ti awọn atọmọ-dọmọ ọmọ wa ba le san owo na ni, ko ye mi si. Ju gbogbo rẹ lọ a dupẹ lọwọ wọn, ki a san owo ilẹ fun awọn ọmọ onilẹ lo ku. Ẹnyin ọmọ onilẹ Eko, ṣe mo ji ọrọ na sọ fun nyin lọjọwo niyin w i p e o w o tabua ti de.

Bi ẹnyin ara Eko ba pe ki ẹ lo ri owo ilẹ yin ti awọn alakoso Ijọba yin gba, ki ẹ maṣe binu r a r a, awọn Oyinbo ti o nrọ owo ẹyọ ni nwọn fi aake kọri wipe awọn kole rọ owo ẹyọ pupọ mọ. Owo pepa ko si ṣe fi pamọ sile fun ọmọlẹbi ki aiperi ki o m a wọọ, paapa owo ilẹ tabi owo ile ti nwọn ba fẹ wo. Mo ti ri iru rẹ ni Oko Awo ati ni ita Akani l'Eko ri. Ọrọ na ko ṣe gbe lọ si Kotu, okun ọmọlẹbi k o si ṣe faja.

## Akintola

Mo gbọ wipe Oloye Samuel Ladoke Akintọla ọmọ wọn ni Ogbomọsho npada lọ si ipo r ẹ gẹgẹbi Alakoso Ijọba Iwọ-Orun ni Ibadan, ati pe awọn ọmọ ẹgbẹ re pelu awọn ọmọ ẹgbẹ Alakuko (N.C.N.C.) ni yio jọ maaṣe ilu, ati pe ọrẹ mi, Oloye J. O. Fadahunsi ọmọ Ilesa tiṣe ọga kan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ Alakuko (N.C.N.C.) na ni nwọn fẹ yan gẹgẹbi Gomina nisisiyi. O KO ! Ede awọn Ijẹbu ni mo fọ yẹn o.

Emi Ayiluka ko ni kunnu kan si ọrọ na, ṣugbọn ti ẹ ba de ijọba yin ki ẹ maṣe gbagbe mi ati ọrẹ mi, Uku Apolopolo Ọmonọbanedo Akenzua Keji, Ọ b a Ibinni. Ki ẹ wa oye minisita kan ki ẹ fi bọwa lapo ki ilu le toro.

Ṣugbọn o dabi ẹni wipe nkankan nfẹ ba ọrọ a nyan Gomina na jẹ, mo gbọ wipe Ọgbẹni T. O. S Benson paapa ndu ipo Gomina na lọdọ awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (N.C.N.C.) ni Ipinlẹ Iwọ-Orun, nitorina ni ariwo ṣe pọ ninu redio pe awọn ti gbe ọ r ọ na le Dọkita Okpara lọwọ ni Enugu. Ki a si m a wo o na ! Ṣugbọn ki a ma ṣe ọrọ na ni ọbẹ tutu adimu ntọla. Ọrọ re o, ẹnyin ọkawe mi.

## Awon "Adele"

Mo gbọ wipe gbogbo awọn ọrẹ mi, awọn "Adele" pajawiri (Commissioner) ti nwon yan ni Ipinlẹ I w ọ Orun ti gba iwe ipalẹmọ wipe nwọn ti ṣe iṣẹ wọn tan ki nwọn ma lọ. Ni ọsẹ to mbọ, ẹ o ma gbọ ọ r ọ diẹ lori iṣẹ wọn lọdọ emi Ayiluka.

Odi gba o !

# Ijoba Gba Die Ninu
## Isura Ile Wa Wasile

EKO—Dię ninu owo iyebiye ti awọn olotu Ijọba Apapọșe wa ni ilę yi ti lọ fi dogo si ilu okere ni a gbọ wipe nwọn ti gba pada wa si ilę Nigeria. Oloye Festu S. Okotie-Eboh, tișe Minisita alamojuto eto owo fi eleyi ye wa ninu ipade kan ti nwọn șe ninu Banki ajọda (Central Bank).

Minisita na tun se alaye si waju wipe gọbọyi ni owo ti Ijọba wa ni ni owo isura (gold reserve) kakiri gbogbo agbaiye, sugbọn gẹgebi awọn ti șe ipinnu fun awọn ara ilu wipe awọn yio mọ gba wọn diędie wa sile ni o jęki awon lọ ru eyi pada wa s'Eko.

Oșelu ka ninu awọn oselu wa șe ẹnu foro fun Onirchin wa wipe o to milion meje pọnun ti nwọn ko wa sile ninu owo na. Nwọn ni orilę ede ti o ba ni owo-isura yi lọwọ ni awọn Ijọba Okere mọ wipe nwọn ni owo lọwọ, iyẹn ni o si nję ki owo ti ilu wọn niyi pupọ, ki o si tun ni iye lori ti nwọn ba fę ra ọja lọwọ awọn Oyinbo onisowo ilu miran.

A tun gbọ wipe nwọn ti ko owo na si ipamọ ninu ile ifowo pamọ si ni Banki ajọda ni ita Tinbu l'Eko.

## Awon Olotu Ijoba Ila Orun Ni Iyorisi Enia Kika Ti Ko jade Ko ye Awon

ENUGU—Awọn olotu Ijọba Ipinlę Ila Orun ni Ẹnugu ni iyọrisi awọn enia ilę Nigeria ti nwọn ti ka lati nkan bi oșu keje ti nwọn kọ lati gbe iyọri rę sita fun gbogbo agbaiye ko ye awọn rara. Eleyi ni Ọgbẹni G. E. Okere, Minisita alamojto eto nkan idagbasoke ilu sọ fun gbogbo awọn ara ilu Ibo ninu ẹrọ onijigin (television) ti o fi sọrọ ni oru ijarun.

Minisita na ni awọn ti fọrọ na logun awọn ti fi lọgbọn lọdọ Ijọba Apapọse l'Eko sugbọn nwọn ko tilę sọ si i rara, dipo eyi, nșe ni nwọn tun nka enia kakiri gbogbo ilę Hausa na. Eleyi ko si ye awọn si rara.

Minisita Okeke ni iyọri si enia kika ti nwọn ka ti nwọn ko gbe jade na nmu ifasęhin wa fun awọn lọdo awọn Oyinbo ajoji ti nwọn fę ba awọn da isę owo pọ.

Minisita na ni eleyi nikan kọ, awọn tun fę mọ iye gbogbo enia ti o wa labę ijọba wọn patapata.

Minisita na ni awọn si ti sọ eyi fun awọn olotu Ijọba Apapọșe l'Eko ki nwọn sọ eyiti nwọn ba fę șe nibę, șugbọn nwọn ni awọn yio pe ipade gbogbo gboo awọn minisita Alamojuto nkan idagbasoke ilu Ipinlę Ijọba gbogbo.

Idi ọrọ re o!

# Moto ayokele kekere

**Awon Oyinbo sese gbe moto-ayokele kan jade, on ni moto ti o kereju laiye, owo ti nwon nta ke si po rara. Ibikibi ni o le gbe pamo si, ko si nje epo pupo, sugbon enia kan lo gba, ko si ibi ti ko le ru e gba; ko ba se inu oko ni tabi arin ilu. Galonu epo kan gbe o tayo Ibadan tati Eko.**



# Eleti – Ofe D'araba

**Enmo LE'ko :**

# Ogbojuole Gbe Moto Onimoto O Fi Nse Takisi Kakiri Ilu Eko

IDDO—Gbogbo awọn oṣiṣẹ ile ibi iṣẹ ọkọ reluwe ati awọn enia ti o fẹ wọkọ lọ si idalẹ ni nwọn pe janajann sori Ọgbẹni awakọ mọto takisi (taxi) kan ti o ko ero ati ẹru wa si idi ọkọ reluwe ni owurọ ana nigbati ọgbẹni kan onimoto ti o ti nwa mọto rẹ ti nwọn gbe lọ lati bi ọdun kan sẹhin lọgun gboo, pe on ri nkan to.

Ọgbẹni ti mọto ayọkẹlẹ rẹ na ti junu si bẹrẹsi ro ẹjọ fun onirohin Eleti-Ọfẹ ti o wa nibẹ lọjọ na. O ni on ni on ni mọto ayọkẹlẹ na, ni ọgba ile on ni on gbe e si loru ọjọ kan ṣugbọn nigbati ilẹ yio mọ ni on fẹ ẹ ku.

O ni on si ti lọ ro ọrọ na lọdọ awọn ọlọpa ti nwọn si sọ fun on wipe awọn wa titi awọn ko ri i; O ni mọto na ni nwọn ti yi ọda ti o wa lara rẹ ki nwọn to jigbe pada.

Onimọto Ọgbẹni na tun ṣe alaye wipe ọda ara rẹ nikan kọ ni nwọn yi pada, nwọn tun yi ami namba (plate number) si ti Ikẹja.

Ẹniti o nwa mọto na ni ki o ṣe on jẹjẹ, ki o ba on ka lọ sọdọ ẹniti o gbee fun on.

Awọn ọlọpa ti tẹsẹ bọ ṣokoto nipa ọrọ na lati ṣe iwadi tani o ji i gbe.

---

**Owo Eyo Fe Sowon Nilu :**

# Awon Oyinbo Ti O Nro'wo Fake Kori

LONDON—Ọrọ owo kiṣe yẹyẹ nibikibi. Awọn Oyinbo merin kan ti o jẹ oṣiṣẹ pataki nile ti nwọn ti nrọ owo orişirişi fun ilu Oyinbo ati awọn ilu ajoji ti fi aake kọri pe awọn kole ṣe iṣẹ ju asiko ti awọn fi adehun si lọ mọ.

Irohin ti a gbọ lati ilu Oyinbo na ni pe awọn kan ninu awọn to ngbẹna sara owo rirọ ti binu kuro nibi iṣẹ na nitoripe nwọn ko fi owo kun owo ti nwọn ngba lọsọsẹ lati bi ọdun meji sẹhin.

Awọn merin miran ni, gbogbo rẹ ti lẹ su awọn, niti awọn, awọn ko le fara da iṣẹ a-ṣe-kudorogbo mọ. Oju owo awọn ni awọn yio maa ṣe.

Awọn ọga ile iṣẹ ti nwọn ti nrọ owo na ni eyi koni jẹki awọn ri aye ko owo tuntun ti awọn fẹ ko ranṣẹ si ilu Nigeria ati ilu ajoji miran ranṣẹ mọ. Nitorina owo-ẹyọ awọn pupọ nita ninu ọdun ti a fẹ bọ si yi.

---

# Oro Woli Ti O Ba

## Woli Lo Ni Sosi De Kotu Olopa

PORT-Harcourt—Adajọ Kotu awọn Ọlọpa ti ngbọ ẹjọ Woli Ṣọṣi awọn ẹgbẹ Serafu ati Kerub, ti o nje Ishmael Ukoli ti o ngbe Diobu ti nwọn ọlọpa mba ro ẹjọ wipe o fi tipa tipa ba ẹmọge woli obinrin kan lo ninu Ṣọsi wọn.

Nigbati nwọn bẹrẹ ẹjọ na Ọmọge Woli yi ti orukọ rẹ njẹ Dorothy ni o kọ sọrọ. O ni on lọ si Ṣọṣi ni alẹ ọjọ ti Woli yi huwa jati-jati yi lati gbe igo "omi-iye" ti iya on ti ara rẹ ko da yio lo.

Dorothy ni bi on ti de ibẹ, on ri ọdaran woli yi, o si ni ki on kunlẹ fun adura niwaju pẹpẹ-adura.

O ni on kunlẹ, on si diju, a fi bi on ti ri ti Woli yi ka on laṣọ lẹhin ti o si wa mọ on papankoko, o si họ'ra fun on.

Dorothy ni Woli arufin yi ti nsọ wipe ki on ati iya on ti ara rẹ ko da, ki awọn jọ ko wa si inu ile on fun "abo" tipẹ.

Adajọ Kotu awọn ọlọpa ti ngbọ ẹjọ na ti sun si ọjọ keji ti nwọn ba ṣe ọdun Keresimesi tan; o si ni ki woli na wa enia duro fun un.

kan ti nwọn kọ si ilu tuntun ti nwọn npe ni Amadi Layout lọjọ Abamẹta ti o kọja yi.

Ni hotẹli yi ni ọmọge na gbe nṣiṣe, ṣugbọn lọjọ ti nkan yi ṣẹlẹ, gbogbo enia ni nwọn pe sibẹ lati ṣ'eyọ "everybody like Saturday Night" ti nwọn ma nṣe lọjọ Satide nu.

Catherine mba Oyinbo ọrẹ rẹ ọkunrin kan jo ijo na ni ọlọjọ ba dẹsii. Awọn ọlọpa si ti ru oku rẹ lọsi ile awọn laku-laku nisisiyi.

---

**HAVE YOU exchanged your OLD WEST AFRICAN COINS for Nigerian Money ?**

FREE EXCHANGE at banks ends on December 31st, 19[illegible]2.

---

# Omoge Kan Jo Ijo-Igba O Ku Bamu-bamu

PORT-HARCOURT—Arẹwa ọmọdebinrin Ibo kan ti orukọ rẹ njẹ Catherine Ewuzie ti o ngbe Opopo Victoria ni Port-Harcourt nibi ni a gbọ wipe o jo ijo - igba kan ti awọn Oyinbo npe ni "Twist" titi ti o fi ṣubu lulẹ ti o si ku bamu-bamu.

Onirohin wa sọ fun wa wipe nkan yi ṣẹlẹ ni hotẹli

---

**E Polowo**

**Oja Yin Sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe**

**Losose**

# ELETI—OFE

ANJUWỌN KO ṢE WI LẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS 28 Kosọkọ Street, Lagos, P. O. Box 468

CABELS & TELGRAME "ELETI—ỌFẸ" LAGOS Phone 23370

VOL XIV· No 547, SATURDAY DEC. 1, - DEC. 7, 1962


# Owolo-wo

Awọn agbalagba ilẹ wa ni bi a ko ba mọ ibiti a gbe nlọ, a mọ ibiti a gbe i mbọ. Irohin kan pataki ti a gbọ ninu ọsẹ yi nipa owo ilu wa ti awọn alakoso Ijọba wa ti fi lọ dogo sọdọ awọn Ijọba Oyinbo nilu okere, ti nwọn si ko diẹ ninu awọn owo na wa sile laipẹ yi, ni o mu awa Eleti-Ọfẹ sọ fun ẹnyin ọkawe wipe OWOLOWO.

Alaye ti awọn alakoso eto owo Ijọba wa ṣe lori iṣura wa na ni pe, gbogbo agbaiye orilẹ ede ti o ba ni golu lọwọ ni o ni iṣura ti awọn Ijọba agbaiye le pe ni Ijọba ti o lowo lowọ ti o si le ra ọja lọwọ awọn onişowo kakiri agbaiye ati pe nitori eyi ni nwọn ṣe ngba wa ni iyanju wipe ki a mọ fi gbogbo ọwọ mewa jẹun mọ.

## Inakuna Nko?

Ọro yi dara leti lati gbọ, şugbọn tani ko mọ wipe awọn alakoso Ijọba wa paapa ni o lu owo apo Ijọba wa ni kunmọ pẹlu inakuna ti nwọn nna lojojumọ.

A ti tun gbọ wipe nwọn tun ngbero lati fi owo iyebiye kọ ile apejọ fun awọn aşoju ti a yan si ile Igbimọ aşofin. Kinni nle nwọn kuro ninu eyiti a ti na ọke aimoye owo lelori ?

Iru owo iyebiye ti nwọn fe na lori ile igbimọ yi, awa Eleti-Ọfẹ gba wọn ni imọran ki nwọn lọ lo lati da iṣẹ silẹ fun ogunlọgọ awọn ọmọ ilẹ Nigeria ti ebi npa ti nwọn ko ni iṣẹ lọwọ.

Ki a mọ ṣe ọrọ na ni ti ẹniti o fi ẹtẹ silẹ ti o upa lapalapa. Ọrọ re o, ẹnyin ara wa!


# Wo Oju Ewe Karun Fun Irohin Ayilnka.


# Iwe Si Olotu

## Alayonuso Ni Odekunle Lori Oro Igbomina

Ẹ jọwọ, Olotu ẹ gba mi laye lati kan saara si ọkawe yin kan ti o pe ara rẹ ni Jekọbu Baba Rachel lori ọrọ alayọnusọ ti Ọgbẹni Ọdẹkunle kọ sinu iwe Irohin Imọlẹ laipẹ yi lori awa ọmọ Igbomina ati awọn ara Ilọrin.

Eyiti o jẹ pato ninu ọrọ na ti Ọdẹkunle ri ti o yatọ si ti Olofintoto Eleti-Ọfẹ ko fi han wa rara. Eleyi wa jẹ ki gbogbo wa mọ wipe ope patapata ni Ọgbẹni Ọdẹkunle na lori rọ u wa na.

Awa ni a mọ ibiti bat ti nta wa lẹsẹ ko şe alayọnusọ bi Ọdẹkunle.

Ẹ jọwọ ẹ ba wa bẹ Olofintoto nyin na wipe eyi ti o ba tun nri gbọ ki o jọwọ ki o maşe fi di wa leti rara.

Olotu, a gbadun iwe nyin na o. Iwaju ni ẹo si ma lọ. Ẹ şe pupọ fun aye ti ẹ gba mi.

Emi ni,
A. Oyeladu .
Oke-Popo,
Eko

## Oro Suru Ni Oro Ilorin

Olotu ẹ gba mi laiye ninu iwe nyin lati kin Olofintoto Eleti—Ọfẹ ti o sọ wipe ọrọ suru ni ọrọ ara Oro pẹlu awọn Ilọrin gba nipa eto Ijọba Ibilẹ ti a ni ki nwọn pin fun wa ki a le ri oju raye mura si ilọsiwaju nkan ilu wa.

Bi oju ko ba ti ole, oju nti onihun. Awa na ri bi nkan ilọsiwaju ti nlọ si ni ilu miran.

Nitoto oju kekere kọ ni a fi ngba ọmọ lọwọ ekurọ aimonkankan ni o nşe Ọgbẹni Ọdẹkunle ti ko joko ara rẹ jẹ ki o mọ woye.

Emi ni,
Gabireli Ọmọ Iludun
Mushin

## Ole Oyinbo Gbe Owo Awon Osise Lo

LONDON— Awọn ogboju ole Oyinbo alawọ funfun kan gbe owo ti nwọn fẹ fi san owo fun awọn oşişẹ ti nwọn nşe işẹ ni idikẹ ọkọ ofurufu ni London nibi; gbogbo owo ti nwọn ja gba lọwọ awọn asanwo na lọ san gangan jẹ ẹgbamarundinlogoji pọnun (£70,000).

Ẹniti o ri awọn ole na ki nwọn to ja owo na gba ni awọn ọlọşa na wọ ẹwu, nwọn si de fila bi ẹniti o nlọ si ibi igbeyawo O ni nwọn to enia mejọ tabi enia mẹwa, nwọn si nyan kiri bi eni wipe nwọn wa şe işẹ kan pataki nibẹ.

Alafojuri na ni ojiji ni on si ri ti nwọn gbe apoti irin kan wọ inu mọto ayọkẹlẹ ti nwọn gbewa.


Y/C January-February 1963

**Nigeria nseto Idagbasoke orile-ede**

Calender jalẹ ọdun 1963

Oşelu ti o nfi ifẹ Ọlọrun şaju ohun gbogbo wọnyi ati jubẹ lọ ni o wa ninu

**YORUBA CHALLENGE**

January-February

**O ti jade fun tita, 4d pere.**

# Aluminium People Open Factory At Apapa

A large number of prominent people gathered at the opening ceremony of the new aluminium factory of the Nigerian Company For Aluminium Limited, otherwise known as Nigerial Ltd, which took place at Wharf Road, Apapa on Thursday last.

The opening ceremony was performed by Alhaji Shehu Shagari, Federal Minister of Establishment, with whom were representatives of all building firms and director of various firms stationed here in Nigeria and all Continental Commercial Heads.

After the introduction of Alhaji Shagari by Monsiur Francois Boccon-Gibod, one of the directors of the company accompanying with a brief speach, the Minister was then called upon to press the button and declared the factory opened.

The minister in his speech said that "It is generally agreed that Nigeria possesses vast potential resources which can be exploited to economic advantage. This has necessarily engaged the minds of the Govement in the direction of Industrial development so as to raise the standard of living of our people and diversify our economy. To this and, the Governments of the Federation are committed to the creation of an atmosphere which is congenial to investments in Nigeria by overseas entrepeneurs. It is gratifying, therefore, to note the responses being made by foreign investors.

"One such response is the establishment of this compliment to the industrialisation of our country by Messrs. Nigerial Limited. This gesture demonstrates the confidence which the founders of this industry have in the future of this country: and I hope that on our part we shall show that that confidence has not been misplaced.

"The parent Company to Nigerial is requted to be one of the leading aluminium companies in Europe with years of experience in the manufacturing of various aluminium products. We hope that the building of this factory by a subsidiary of that reputable European Company will not only satisfy the needs of Nigeria for modern roofing materials but will also occasion the acquisition by Nigerians of useful skills and technical knowledge. In addition, there is no doubt that the opening of this factory will offer more business opportunities for those of our people who possess the initiative and drive."

After the ceremony the guests were served with refreshments. Other Nigerian directors of the Company were Messrs Alex Oni and Taju Thompson.



The above picture taken during the opening of Aluminium Factory at Apapa shows from left Monsuir Francis Boccon-Gibod (a Director of the Company), Alhaji Shehu Shagari, Federal Minister of Establishment, Messrs Alex Oni and Taju Thompson, other directors of the Company.

## More Nigerians Called To The Bar

LONDON— Twenty-two Nigerians have been called to the Bar in the Michaelas Term at Lincoln's Inn, London this week. They are: Olusanya Ajayi B.Sc. (Econ), of 23 Adeti St., Ilesha; Rasheed G. Fetuga, LL.B., of 18, Ikangbo St., Ijebu-Ode; Johnson O Ajayi, of Ifolu St., Ipetu-Ijasha Benin City; Samson Adeniyola of Idofin St. Iddo Fanoro; Benedict O. Anyaduba, of 3 Court Rd., Onitsha.

Olusola O Fakeye, of Vula Esie, Northern Nigeria; Umozurike, LL.B., of Obinkita Arochukwu; Bandele O Olatunji, LL B, of 65, Oke-Dasa St, Ondo Julius, S. Anyanwu LL.B (Hons.), of Enyiogagu, Mbaise, Owerri; Aaron A. Lambo, of 66 Pedro St., Lagos; Idowu O. Sonoiki, of Oke-Bola, Ibadan; Sidney A. Afonja, B.A., B.C.L., LL.B. (Hons.) of Ado-Ekiti; Sunday O. Chinke, LL.B., of Oboro, Umuahia; Bolasodun A. Ajibola, LL.B., of Afin-Olowu, Ago Owu, Abeokuta.

## Pumps For Nigerian Sugar Irrigation

LONDON — A British firm is building a pumping installation for Nigeria's new sugar plantation at Bacita which will draw 45,000 gallons of river water a minute for irrigation.

Ordered by the Nigerian Sugar Company, the installation, worth £37,000, is being built by Gwynnes Pumps Ltd., at Welling Foundry, Lincoln, and one of the firm's engineers will go to Northern Nigeria to supervise the installation.

The plant, which comprises three pumps, motors and pumphouse crane, should be running by mid-December, 1963.

# Awon "Adele" Ijoba Iwo Orun

## TI NPALEMO ILE

IBADAN — Awọn enia pataki mọkandinlogun kan ti nwọn yan si ipo adele awọn minisita alamojuto iṣe Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun nigbati rogbodiyan de si Ibadan ti gba iwe pe iṣẹ wọn tan ki nwọn ma ṣe ipalẹmọ lati pada s'ẹnu iṣẹ olukuluku wọn.

Olufintoto "Eleti-Ọfẹ ni on gbọ wipe ọsẹ mẹta ni nwọn fun wọn ninu iwe na lati fi se ipalẹmọ na. Mo gbọ wipe ti o ba di ọjọ mẹdogun oṣu ti a ṣẹṣẹ bọ si yi olukuluku awọn adele nwọnyi yio ti lọ si ile wọn.

Mo gbọ wipe ofin pajawiri paapa fẹ ka ẹsẹ nilẹ laipe yi, Oloye Akintọla a si pada si ipo ti nwọn ti yọ o kuro gẹgebi alakoso Ijọba Ipinlẹ na, ṣugbọn ko da mi loju pe gbogbo awọn minisita ti Ijọba atijọ ni yio pada si ipo wọn.

Mo gbọ wipe nwọn a ro ọrọ na ṣe larin awọn ọmọ ẹgbẹ Alakuko (NCNC) ati ẹgbẹ Ọlọmọ.

## Ara Popu Ko Da Rara

ROME—Ọlọrun ni o mọ ilẹ ti o le mọ ba ọjọ ọla, iyẹn ni ti ọrọ Ẹni-ọwọ Pope John. Olori gbogbo ijọ awọn Aguda ti a ri waya gba pe o nṣe amọdi lọwọ lọwọ bayi, ti awọn Padi si nṣe ki gbogbo ẹgbaiye gba akanṣe adura fun wipe ki o le bọ ninu amodi na.

Gegebi irohin ti a gbọ, ninu ọsẹ yi ni Olori awọn ljọ Ṣọṣi Aguda yi ṣe ajọyọ ọjọbi ọdun mọkanlelogorin ti o ti de aiye.

Onirohin wa ni on gbọ wipe amọdi na le tobẹgẹ ti dokita atata kan ti o ma ntọju awọn Popu ti nwọn npe orukọ rẹ ni Professor Antonio Gasbarrini, sọ wipe on ni lati ṣe iṣẹ abẹ fun Ẹni-ọwọ na ki on le yọ nkan ti o ndun lọfun kuro.

Ẹni-ọwọ Popu na ko le lọ si apejọ gbogbo awọn Aguda ti nwọn wa ṣe ẹsin nilu Romu lati ba wọn sọrọ ati lati ba wọn gba adura.

## Owo Te Enahoro Ni Ilu Oyinbo

LONDON— Ọwọ Ọlọpa tẹ Oloye Anthony Enahoro ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ ọlọpẹ ti awọn ọlọpa ti nwa kiri lori ẹjọ ọtẹ ti awọn si nse lọwọlọwọ ni Kotu-ganran l'Eko.

Oyinbo ọlọpa'nu ti o mu u ni on tọ lọ ni owurọ ijarun ninu ile ti o de si ni London, on sọ fun un wipe on fẹ fi aṣẹ Ọba mu fun ofin kan ti o ru fin o to sa kuro ni Nigeria. Nwọn gbe Enahoro lọ siwaju adajọ kotu kan wipe ki o fun awọn laṣẹ ki awọn le mu wa sile lati jẹ ẹjọ rẹ.

Adajọ kotu na ni on le ti fọwọ si nitoripe isansa oṣelu ni lọya rẹ pee, o si nwa ibiti yio gbe fori pamọ si ni fun ruke-rudo ti bẹ si'ẹ ninu ilu rẹ. Ju gbogbo rẹ lọ, adajọ ni ki nwọn si lọ fi Enahoro pamọ si itimọle di ọjọ Ọjọru (Wednesday) ọjọ marun loni ki on to mọ nkan ti on yio ṣe si ọrọ rẹ.

## Ijoba Gbe Ofin Le Awon Onitete

IBADAN—Lati ọjọ oni lọ ko si ẹnikẹni ti o gbọdọ gbe iwe tẹtẹ-tita jade lai fi owo gba iwe-aṣẹ (licence) ni ọwọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun, eyi ni iwe ti awọn Alakoso Ijọba Iwọ Orun na gbe jade ni oru ana.

Nwọn paa laṣẹ ninu iwe ofin na wipe ki ẹnikẹni to gbe iwe tẹtẹ-bọlu (pools promoter) jade o ni lati san ọgọrun pọnun sarai si apo Ijọba fun iwe aṣẹ ọdun kan. Awọn ti o ba si jẹ iṣẹ aṣoju (agent) ni awọn gba, awọn na ni lati san pọnun mẹwa mẹwa fun iwe aṣẹ ile kọkan ti nwọn ba mba wọn gba iwe na. Olukuluku ti o ba si ti gba iwe-aṣẹ na ni lati lẹ mọ ibi kan pataki ninu ile na ki gbogbo enia le ma rii.

A gbọ wipe gbara ti awọn ẹgbẹ onitẹtẹ ilu Ibadan, awọn enia dudu ati awọn Kọra ti o fi tẹtẹ-bọlu ṣe iṣẹ ṣe ni nwọn fọn'mu, ti nwọn kawọ leri pe ki awọn Olotu Ijọba na ko gba awọn, ki nwọn wo o ṣe fun awọn. Awọn ko sọ wipe awọn ko fẹ lati gba iwe-aṣẹ ṣugbọn owo-ere (commission) ti Ijọba ni ki awọn tun ma san lori owo ti ko ti wọle fun awọn yi ni o jẹ nkan ti ko ye awọn.

Nwọn ni ki awọn Olotu Ijọba gba awọn lori ọrọ na. Baba-ẹgbẹ wọn Ọgbẹni Afọlabi James ni iṣẹ tẹtẹ ti awọn npe ni fixed odds iṣẹ abiku ni ko da bi ti tẹtẹ-bọlu keji ti nwọn npe ni Treble Chance, ajọ ni eleyi, owo ti awọnenia ba dajọ ni awọn nha fun wọn.

Ọrọ na ko ti loju rara, onirohin wa ni gbogbo awọn Kọra a-ta-tẹtẹ ni nwọn si ti ko igba tẹtẹ-tita wọn sile.



**Oloye Awolowo**

(O bẹrẹ loju ewe kinni (...

Oyinbo awọn Ọlọpa'n... J-hn Lynn, sọ fun ada... bi on ṣe lọ si inu ile k... ni Ijẹbu-Ode ti on ri Apo... ti ti nwọn di ibọn a... ọta-ibọn si. Oyinbo na... on ko gbogbo rẹ ati aw... ran Awolọwọ ti on ri ni... O ni on ko ri ẹnikan ni i... iyara na ṣugbọn iwe... nwọn sọ wipe o wa ni... awọn apoti na.

RECORDS

78 RPM at 7/- each
P.825227H
Orin TunTun Tele Kiniken
Nieru Bami & Aroworeyin & His Group
P.81501 H
Toba lowo Mayo Layoju
Oluwa Loluso Agutan
Federal Rhythm Brothers
P.82528 H
Olo Mi Atata/Abiodun Oniboekun C. A. Balogun and His Abalabi Orchestra Ibeira
45 RPM at 6/9d each
P.382447 F
Ko Forun/Papiago Davalaya
Victor Olaiya & His "All Stars"
P.382462 F
Otan Bebrebe yi/Me Regrets Mo
E.K'S Band.

PHILIPS
of course...
—the records of the century—

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 3370 EDITOR (OLOTU) OLA ONATADE
15, Kosoko Street, Lagos.